# KRISTI ATI MELKISEDEKI

Heberu 6:13-20;  7:1-28.

ẸKỌ 438  --  FUN AGBA

AKỌSORI:  "Nitoripe irú Olori Alufa bẽ li o yẹ wa, mimọ́, ailẹgan, ailẽlẹri, ti a yà si ọ̀tọ kuro ninu ẹlẹṣẹ, ti a si gbéga jù awọn ọrun lọ" (Heberu 7:26).

## Abrahamu ati Ihinrere

**"Bi iwe-mimọ́ si ti ri i tẹlẹ pe, Ọlọrun yio dá awọn Keferi lare nipa igbagbọ́, o ti wasu ihinrere ṣaju fun Abrahamu, o nwipe, Ninu rẹ li a o ti bukún fun gbogbo orilẹ-ède" (Galatia 3:8).**

Nitori naa, ninu ileri ti Ọlọrun ṣe fun Abrahamu, (Gẹnẹsisi 12:1-3) a ni ipilẹ ati idagbasoke Ihinrere.  Ileri ti o jẹ mọ Ihinrere ni eyi.  Paulu n fi idi rẹ̀ mulẹ pe ninu ileri yii, Ọlọrun ti n waasu Ihinrere fun Abrahamu. Ihinrere ti wà ni ipo alakọbẹrẹ eyi ti a fun ni ni oji-le-ni-irinwo ọdun o dín mẹwaa (430) ṣaaju Ofin, nitori naa, Ihinrere ti wà ṣaaju Ofin.

Abrahamu jẹ́ ẹni ọgọrin ọdun o din marun-un nigba ti Ọlọrun ṣe ileri fun un, nigba ti o si bi Isaaki, o jẹ ẹni ọgọrun ọdun; nitori naa o fi suuru duro fun ọdun mẹẹdọgbọn.  Ọdun ti Paulu n tọka si ni eyi nigba ti o n fi Abrahamu ṣe apẹẹrẹ ẹni ti o fi suuru duro.  Lẹyin ti o ti fi suuru fara daa, o ri ileri naa gbà.  Siwaju si i, a kà bayií ninu Heberu 10:36, pe:

**"Nitori ẹnyin kò le ṣe alaini sũru, nitori igbati ẹnyin ba ti ṣe ifẹ Ọlọrun tan, ki ẹnyin ki o le gbà ileri na."**

Abrahamu gba Ọrọ Ọlọrun gbọ́ ni ẹsẹkẹsẹ.  Bi Ọlọrun ti pe e, o dide ni ẹsẹ̀ kan naa, o fi awọn ẹbi, iyekan ati ilu rẹ̀ silẹ, ati nipa igbagbọ́, o lọ si ilẹ ti oun kò mọ ri, eyi ti oun yoo gbà nigbooṣe gẹgẹ bi ini.  O jẹ́ ọdun mẹẹdọgbọn gbako ki a to mu ileri yii ṣẹ fun un eyi ti yoo sọ iru-ọmọ Abrahamu di ibukun fun gbogbo idile ayé.

**"Kò fi aigbagbọ ṣiyemeji ileri Ọlọrun, ṣugbọn o le ni igbagbọ́, o n fi ogo fun Ọlọrun" (Romu 4:20).**

Nitori naa, igbagbọ ni o mu Abrahamu la gbogbo akoko naa já ti o si fun un ni suuru.  Bi a ba fẹ ni suuru, a ni lati ni igbagbọ́, iru eyi ti Abrahamu ni.  Pipẹ́ Ọlọrun ki i ṣe ifiduni.  Nigba pupọ ni Ọlọrun n fa imuṣẹ ileri Rẹ̀ sẹyin; ṣugbọn nigba ti O ba ṣe ileri, yoo mu un ṣẹ dandan!  Oun ko le ṣai mu ileri yii ṣẹ nitori o jẹ mọ Ihinrere.

## Ifidimulẹ Ileri Ihinrere

**"Ninu eyiti bi Ọlọrun ti nfẹ gidigidi lati fi aileyipada imọ rẹ̀ han fun awọn ajogún ileri, o fi ibura sãrin wọn" (Heberu 6:17)**

Gẹnẹsisi 22:16-18 jẹ atunsọ ileri iṣaaju ti O ṣe eyi ti O wá fi idi rẹ̀ mulẹ nipa ibura nihin.  Gẹgẹ bi ẹni ti o kọ iwe Heberu ti sọ pe, "Bi kò ti ri ẹniti o pọju on lati fi bura, o fi ara rẹ̀ bura."  Nitori naa, a ni ileri Ihinrere ni oji-le-ni-irinwo ọdun o din mẹwaa (430) ṣaaju Ofin, eyi ti a fi idi rẹ̀ mulẹ pẹlu ibura. Nigba ti Oluwa fi ara Rẹ̀ bura nitori Ẹni ayeraye ni Oun, itumọ eyi ni pé kò si ohun ti o le yi ileri naa pada – o duro laelae.

Bi o bá ṣe pe o ti fi ọrun ati ayé bura, eyi ti yoo wá si opin, ibura Rẹ̀ i bá wá si opin nigba ti awọn ọrun ati ayé bá ká kuro. Ṣugbọn O fi ara Rẹ̀ bura lati fi hàn pé igbimọ Oun kò le yi pada. O duro laelae.

Nitori naa, Ofin ti a fi fun ni ni ori Oke Sinai ko le sọ ileri ti Ọlọrun ṣe fun Abrahamu ti a si fi ibura fi idi rẹ̀ mulẹ, di asán. A fi ibura fi idi ileri naa mulẹ, ṣugbọn a kò ṣe bẹẹ fun Ofin. Bi o bá ṣe pe ibura ni o fi hàn pe ileri naa ki yoo yẹ̀ lae, ati pe a kò fi ibura si Ofin ti a fi fun ni ni oji-le-ni-irinwo ọdún o din mẹwaa (430) lẹhin naa, eyi fi han pe, a le pa Ofin tì si apa kan.

**"Pe, nipa ohun aileyipada meji. . ."**

Awọn ohun aileyipada meji naa ni ileri Rẹ̀.  Lọna kin-in-ni, ileri Rẹ ko le yipada ati pe ibura Rẹ̀ ti o fi idi ileri naa mulẹ mu ki aileyipada naa ki o di ilọpo meji.

**" . . . ninu eyiti ko le ṣe iṣe fun Ọlọrun lati ṣeke, ki awa ti o ti sá sabẹ ãbo le ni iṣiri ti o daju lati di ireti ti a gbé kalẹ niwaju wa mu" (Heberu 6:18).**

Ireti yii ni a muṣẹ ninu Kristi Jesu. Ileri nì a ṣe fun Abrahamu jẹ́ akọbẹrẹ. Ihinrere ṣẹṣẹ hù jade ni igba naa ni; ṣugbọn diẹdiẹ, ni ṣisẹ-n-tẹle, ni ẹsẹ le ẹsẹ ni o n yọri jade: nipa apẹẹrẹ, nipa irubọ, nipa isin Tẹmpili, nipa ilana awọn alufaa ati isin wọn. Iṣisẹ kọọkan ni o n tọka si imuṣẹ idagbasoke Ihinrere eyi ti Kristi Jesu ṣe aṣepari rẹ̀ ni gbogbo ọna. Nitori naa Jesu wá di ireti wa. Ohun ti Paulu sọ nipa Rẹ̀ ni eyi:

**"Paulu, Aposteli Kristi Jesu, gẹgẹ bi aṣẹ Ọlọrun Olugbala wa, ati Kristi Jesu ireti wa" ( 1 Timoteu 1:1).**

Kristi Jesu ni ireti naa lonii. Gbogbo awọn asọtẹlẹ Majẹmu Laelae ni o n tọka si Jesu Oluwa, Ẹni ti i ṣe ireti gbogbo awọn ti i~~I~~ ṣe iru ọmọ ileri naa lonii.

**"... ki awa le ni iṣir~~u~~i ..."**

"Iṣiri" tabi itunu ni itumọ ti o ga ju iro ọkàn l~~a~~asan. O ni itumọ imuṣẹ ti ko si ohun miiran ni ayé yii ti o le mu iru imuṣẹ bẹẹ wà; lori eyi ti gbogbo ireti wa, ilepa ati ifẹ wa duro le.

**"... ti o ti sá sabẹ ãbo le di ireti ti a gbé kalẹ niwaju wa mu."**

Eyi n tọka si awọn Ilu Aabo ti o wà ninu Majẹmu Laelae. Awọn Ilu Aabo yii jẹ́ apẹẹrẹ Kristi. Ninu Kristi Jesu, a ni Ilu Aabo ti a le sá lọ nigba ti ọta ba n le wa; ti a ba si ti wọ inu rẹ̀ lọ, a ni aabo ti o daju kuro lọwọ agbẹsan ẹjẹ.

**"Eyiti awa ni bi idakọ̀ro ọkàn, ireti ti o daju ti o si duro-ṣinṣin, ..."**

Nihin in, aworan ti a fi si iwaju wa yipada o si n tọka si ọkọ̀ ti o wà lori òkun ti igbi n ti i~~I~~ sihin ati sọhun.

### Melkisedeki ati Kristi

**"... ti o si wọ̀ inu ile lọ lẹhin aṣọ ikele;**

**"Nibiti aṣaju wa ti wọ̀ lọ fun wa, ani Jesu, ti a fi jẹ Olori Alufa titi lai nipa ẹsẹ Melkisedeki."**

Paulu tun n ba ọrọ rẹ̀ lọ, eyi ti o sọ ni ori karun-un nipa Melkisedeki.

O dá ọrọ yii duro lati fi àye fun ọrọ iyanju ati ikilọ nipa ipada kuro ninu igbagbọ́.

Ninu Gẹnẹsisi ori 14 ni a kọ́ mẹmu ba Melkisedeki. Nigba ti Abrahamu n pada bọ̀ ninu ilepa awọn ọba ti o ti wá si Sodomu lati kó Lọti ati awọn eniyan rẹ̀ ni ẹrú, Abrahamu gba gbogbo ẹrù ti awọn ọba naa ti kó lọ, o si gba Lọti ati awọn ara ile rẹ̀ pada si Sodomu.

Nigba ti Abrahamu ati awọn eniyan rẹ̀ n pada bọ̀, Melkisedeki, Ọba Salẹmu wá pade rẹ̀ lati ki i ati lati fun un ni ohun itura fun jijẹ. O bukun fun Abrahamu; lai si aniani ibukun yii jẹ́ atunsọ ire kan naa ti Ọlọrun ti sú fun Abrahamu ni iṣaaju: pe oun yoo jẹ baba orilẹ-ede nla, ati pe nipa rẹ̀ ni a o ti bukun fun gbogbo idile aye. Abrahamu mọ ipo Melkisedeki pe oun ni alufaa Ọlọrun Ọga-Ogo. Abrahamu san idamẹwaa ikogun naa fun un. Bi o ba ṣe pe bi gbogbo ọrọ naa ti mọ ni eyi, ọrọ afi-ẹnu-ba-fisilẹ ni i ba jẹ́. Ṣugbọn eredi ti o fi jẹ pataki ju lọ ni pe ẹẹdẹgbẹta (500) ọdun lẹyin eyi, Dafidi sọ bayii ninu Orin Dafidi 110, pe:

**"OLUWA ti bura, ki yio si yi ọkàn pada pe, Iwọ li alufa titi lai nipa ẹsẹ ti Melkisedeki" (Orin Dafidi 110:4).**

Orin Messia ni eyi i ṣe. Nihin yii, Oluwa Jehofa n sọ ọrọ wọnyii si Messia pe: "OLUWA wi fun Oluwa mi pe," nitori naa asọtẹlẹ nipa Kristi ni eyi.

Kò si ibomiran mọ́ ninu Ọrọ Ọlọrun ti a tun mẹnu kan Melkisedeki afi ori karun-un Iwe Heberu ni ibi ti a ti ri alaye nipa ẹni iyanu yii, Melkisedeki. O ṣe danindain pe ki ọrọ yii fi idi mulẹ ninu ọkàn wa nitori o fi ara kan ipò oye Jesu Kristi.

Alufaa ni Melkisedeki i ṣe, ki i ṣe lati inu iran Abrahamu ni o ti wá. O ṣe e ṣe ki o jẹ́ eniyan kan ti o ti ri Ọlọrun Olootọ ati Alaaye, boya lai si ninu awọn iṣipaya Ọlọrun ni itosi, gẹgẹ bi ti Jobu, tabi bi i ti awọn amoye ti o wá si ọdọ Jesu. Wọn ri Ọlọrun Alaaye ati Otitọ. Awọn miiran tilẹ gbagbọ́ pe Jesu Kristi ni Melkisedeki i ṣe. Ṣugbọn ohun ti a mọ̀ ni pe ẹni iyanu ni.

**"Laini baba, laini iyá, laini itan iran, bẽni kò ni ibẹrẹ ọjọ tabi opin ọjọ aiye, ṣugbọn a ṣe e bi Ọmọ Ọlọrun; o wà li alufa titi" (Heberu 7:3).**

Pe oun ko ni baba ati iya le tumọ si pe, a ko sọ ohunkohun nipa itan iran rẹ̀. Eyi yatọ si ilana ti iṣẹ alufaa awọn Lefi. Wọn fi ọwọ danindanin mu ọrọ iran wọn nitori lati inu iran wọn ni wọn ti n ṣe eto oye alufaa, lati ri i pe o bá ofin Mose dọgba.

Ṣugbọn nihin ni a ri alufaa ti Ọlọrun Ọga-ogo ti kò ni iran. O fi ara han ninu iwe itan o si di afẹku, lai ni ibẹrẹ, tabi opin. Ẹni ti o kọ Iwe Heberu fi eyi ṣe apẹẹrẹ Kristi, nitori ohun ti Dafidi ṣe itumọ rẹ̀ si ni eyi nigba ti o wi bayii pe "Iwọ li alufa titi lai nipa ẹsẹ ti Melkisedeki." Eyi ni Melkisedeki naa ti i ṣe apẹẹrẹ ipo oye alufaa ti Jesu Kristi ti o wá lẹyin naa.

**Ọba ati Alufaa**

**"Njẹ ẹ gbà a rò bi ọkunrin yi ti pọ̀ to, ẹni ti Abrahamu baba nla fi idamẹwa ninu awọn aṣayan ikogun fun."**

Iba diẹ ni a sọ fun ni nipa rẹ̀, eyi ko si jẹ ki a mọ pupọ nipa bi oun ti ga to, afi eyi pe: oun ni alufaa Ọga-ogo, ati pe ọba ni, eyi ti o tun mu iyatọ wá nipa ipo oye alufaa gẹgẹ bi ilana awọn Lefi. Ko si ẹni ti o jẹ ọba ninu wọn ri; alufaa nikan ni wọn. Ṣugbọn Melkisedeki jẹ ọba ati alufaa ni ilu ti o ṣe pataki ju lọ ni Ilẹ Ileri—Salẹmu, eyi ti o wá di Jerusalẹmu.

Awọn ipo oye wọnyii ni Jesu Kristi paapaa di mú, ati eyi ti a pe E, ti a si yan An si. O bẹrẹ iṣẹ Rẹ̀ gẹgẹ bi Wolii nigba ti a ri I bọmi ti ita-ororo-si Oluwa si wá si ori Rẹ̀ ti o si bẹrẹ iṣẹ iranṣẹ Rẹ̀. O bẹrẹ iṣẹ Alufaa Rẹ̀ nigba ti o goke re ọrun ti awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ko ri I mọ́ nigba ti wọn pe jọ ni ori oke Olifi. O wọ Ibi Mimọ julọ ni Ọrun. Oun yoo bẹrẹ oye Rẹ̀ gẹgẹ bi Ọba nigba ti O ba fi Itẹ ilaja silẹ ti O si pada bọ̀ wa si ayé yii ni ẹẹkeji.

Ṣugbọn Oun ti gba ipo oye wọnyii lai ka igba ati akoko si. Bi apẹẹrẹ, Pilatu wi fun Un pe, "Iwọ ha li Ọba awọn Ju?" O dahun, O si wi pe, "Iwọ wi i." O jẹ́ Ọba ni igba naa bi o tilẹ jẹ pe ko ti i gun ori Itẹ Rẹ̀. Bakan naa ni O jẹ Wolii ati Alufaa ni akoko kan naa. Nitori naa iṣẹ Rẹ̀ gẹgẹ bi Alufaa, Wolii ati Ọba wà titi lai si ibẹrẹ ati opin.

**Abrahamu ati Melkisedeki**

Ki a to le mọ bi Melkisedeki ti pọ̀ to, o yẹ ki a ni oye diẹ nipa bi Abrahamu ti ga to. Nihin Abrahamu wà ni ilẹ awọn ara Kaldea. Ninu Iṣe Awọn Apọsteli, a sọ fun ni ninu ọrọ Stefanu pe Ọlọrun ti pe Abrahamu ni Uri ṣaaju ki o to pe e ni Harani. O kan ti duro fun igba diẹ ni Harani ni boya nitori aisan baba rẹ̀ ti o yọri si ikú ni ibẹ. Ni igba naa ni a tun un pe ni Harani. Ọlọrun pe e jade kuro ni aarin awọn arakunrin, awọn eniyan rẹ̀ ati kuro ni orilẹ-ede rẹ̀, si ilẹ aimọ̀.

Ni ibẹ ni o ti dan an wo: Ọlọrun dán suuru, igbagbọ́ ati ifarada rẹ̀ wò. Nitori Abrahamu yege ninu gbogbo idanwo naa, o di ori fun orilẹ-ede nla ati nipa rẹ̀ ni a ti bukun fun gbogbo idile ayé. Lati ipasẹ rẹ̀ ni irú nì yoo ti wa ti yoo jẹ orisun ibukun ti Ọlọrun ti ṣe ileri fun Abrahamu. Oun ni o pọ ju ninu awọn baba nla-baba igbagbọ́. O duro bi apẹẹrẹ ohun ti Ọlọrun le ṣe fun eniyan bi o ba jọwọ ara rẹ̀ patapata fun Ọlọrun, gẹgẹ bi Abrahamu ti ṣe.

Sibẹ Melkisedeki pọ ju Abrahamu lọ: Abrahamu san idamẹwaa fun un, Melkisedeki si sure fun un. Ẹni ti o pọ ju ni o sure fun ẹni ti o kere. Otitọ ni eyi pẹlu nipa sisan idamẹwaa. Abrahamu mọ titobi ọkunrin yii.

Labẹ Ofin, awọn ọmọ Lefi ni o n gba idamẹwaa. Oun ni wọn n jẹ. Ṣugbọn Abrahamu ni ori ati baba ilana oye alufaa ti awọn Lefi, o si ga ju wọn lọ, sibẹ o san idamẹwaa fun Melkisedeki ; o mọ ipo ati aṣẹ Melkisedeki.

**Iyipada Ipo Oye Alufaa**

Kiyesi i, oye alufaa ati Ofin ko ṣe e yà si ọtọ. Igbekalẹ oye alufaa wà fun pi~~o~~pa Ofin mọ́, ki a ba le pa ofin mọ ninu gbogbo iṣẹ-isin ti Ọlọrun ti là silẹ. Nitori naa, wọn ko ṣe e ya ni ipá; wọn ni lati duro pọ tabi ki wọn ṣubu pọ.

**". . . kili o si tún kù mọ́ ti alufa miran ba fi dide nipa ẹsẹ Melkisedeki." (Heberu 7:11).**

Bi Ọlọrun ba ti ṣe ilana rẹ̀ pe gbogbo ohun ni a oo muṣẹ nipa ẹsẹ ipo oye alufaa nipa Lefi ti O ti yàn, eredi wo ni a tun ṣe fi àye silẹ fun ipo oye alufaa miiran? Ko yẹ ki a tun fi àye silẹ fun omiran. Ninu eto ilana Ọlọrun, aye diẹ ni o wà fun eto oye alufaa nipa ẹsẹ awọn ọmọ Lefi. O ti ṣiṣẹ ti a là silẹ fun.

**"Nitoripe bi a ti pàrọ oyè alufa, a kò si le ṣai pàrọ ofin."**

A pa ofin ni rẹ́ ti o wà ṣaaju dide Ofin Titun. Ofin Atijọ nì ti kuro, kò ni agbára mọ́.

### Ailera Ofin

**“Nitori ofin kò mu ohunkohun pé, a si mu ireti ti o dara jù wá. . .” (Heberu 7:19).**

Njẹ eyi yé wa pe kò si olododo ni igba aye Ofin? Tabi pe nitori ikuna ti o wà ninu Ofin, o ṣoro lati ri ododo gbà? Paulu sọ oju abẹ niko nigba ti o wi bayii pe:

**“Nitori ohun ti ofin kò le ṣe, bi o ti jẹ alailera nitori ara, Ọlọrun rán Ọmọ on tikararẹ̀ li aworan ara ẹ̀ṣẹ, ati bi ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ, o si da ẹ̀ṣẹ lẹbi inu ara:**

**“Ki a le mu ododo ofin ṣẹ ninu awa, ti kò rin nipa ti ara, bikoṣe nipa ti Ẹmi” (Romu 8:3, 4).**

Ailera ofin lati mu ni di pipe ko wá nipa ikuna tabi aipe Ofin funra rẹ̀; aipe naa wà ninu eniyan nipa aile pa gbogbo ilana Ofin mọ.

### Ireti Ti O Dara Jù

**“. . . . a si mu ireti ti o dara jù wá; (ireti ti o dara ju naa ni Jesu Kristi) nipa eyiti awa nsunmọ Ọlọrun” (Heberu 7:19).**

A mu eyi wá lati fi iyatọ ti o wà ninu Isin Agọ atijọ hàn ninu eyi ti awọn eniyan n duro sun mọ itosi nigba ti Olori Alufaa ba lọ si Ibi Mimọ Julọ lati sin. Awọn ijọ yoo sun mọ ẹnu Agọ, wọn yoo si maa jọsin nigba ti Olori Alufaa ba n ṣe iṣẹ isin ni Ibi Mimọ Julọ ni Iwaju Itẹ Aanu.

**“Niwọn bi o si ti ṣe pe ki iṣe li aibura ni a fi jẹ alufa.”**

Ileri ti a ṣe fun Abrahamu nipa Majẹmu Titun ati oye alufaa nipa ẹsẹ Melkisedeki ti wà ṣaaju ki ofin to de. A fi wọn fun ni pẹlu bura, awọn mejeeji ni o si bori Ofin. Nitori ti a fi ibura fi idi wọn mulẹ, mu wọn wa lodi si Ofin nitori a ko fi ibura fi ẹsẹ oye alufaa igba ni mulẹ. Ọlọrun fi ara Rẹ bura nitori ti ko si ẹni ti o ga ju U ti O tun le fi bura, pe awọn ileri mejeeji, fun Abrahamu ati ipo oye alufaa nipa ẹsẹ Melkisedeki jẹ́ ti ayeraye – ti kò si ni opin.

**“Niwọn bẹ̃ ni Jesu ti di onigbọ̀wọ́** (itumọ “onigbọ̀wọ́” ni “alarina”) **majẹmu ti o dara jù” (Heberu 7:22).**

Ọrọ ti a n pe ni “Majẹmu” on kan naa ni a tumọ si “adehun” ni ibomiran. Nigba ti a ba n sọrọ Majẹmu Laelae ati Majẹmu titun, a tun le pe e ni Adehun Laelae ati Adehun Titun nitori tẹlẹ ri ọkan naa ni awọn ọrọ mejeeji. Nibẹ O di alarina Majẹmu ti o dara jù.

### Alufaa Titi Lae

**“Ati nitõtọ awọn pupọ̀ li a ti fi jẹ alufa, nitori nwọn kò le wà titi nitori ikú.”**

Aṣipo-rọpo wà ni iran Aarọni, nitori ipo oye alufaa kò gbọdọ wà lofo. Ṣugbọn a gbọdọ maa fi eniyan si ipo naa lati iran dé iran lati inu iran Aarọni. Ṣugbọn nihin, eyi ko wulo mọ́ nitori Ẹni kan ni yii ti a fi jẹ nipa agbára ti iye ailopin: nitori naa ko si eto fun arọpo, ṣugbọn Alufaa kan ti o wà titi laelae.

### Gbigbala Titi De Opin

**“Ṣugbọn on, nitoriti o wà titi lai, o ni oyè alufa ti a kò le rọ̀ nipò.**

**“Nitorina o si le gba wọn là pẹlu titi de opin. . . .”**

“Titi de opin” jẹ ọ̀kan ninu awọn ọrọ ti wà ni ede Griki ti o n fi ẹsẹ̀ nnkan mulẹ. Ko tumọ si igba nikan – wiwa laelae -- ṣugbọn o tumọ si pipé – ani igbal~~o~~a pipé ati kikún.

Kò si abuku ninu igbala ti Oluwa n fi fun eniyan. Bi abuku tabi ikuna tabi ohun kan ba wà ti o fi hàn pe boya igbala ṣe alailera, ranti pe ki i~~I~~ ṣe ninu igbala ni abuku tabi ailera naa wà. Bi ailera kan bá wà, ninu ẹni ti o kuna lati di Oluwa mu ki o ba le ni agbára to lati duro ni ailera wà. Igbala yii wa titi de opin. Itumọ eyi ni pe, ki i ṣe pe igbala jẹ́ pipé nikan, ṣugbọn o k~~u~~ún, o si ká gbogbo ipẹkun ayé, o wà fun gbogbo eniyan, orilẹ ati ède, olukuluku eniyan lọkunrin ati lobinrin.

### Olori Alufaa Alailẹṣẹ

**“. . . . ẹniti o ba tọ̀ Ọlọrun wá nipasẹ rẹ̀, nitoriti o mbẹ lãye titi lai lati mã bẹ̀bẹ fun wọn.**

**“Nitoripe irú Olori Alufa bẹ̃ẽ li o yẹ wa, mimọ́, ailẹgan, ailẽri, ti a yà~~á~~ si ọ̀tọ kuro ninu ẹlẹṣẹ, ti a si gbéga jù awọn ọrun lọ.”**

Nję ohun kan wà ti o yę ki a sọ ti a ko i ti i sọ? Eyi ni pe “lai si ikiweje, pipe patapata” nipa ti ẹmi -- Ọlọrun mimọ́ tikara Rẹ̀ pẹlu gbogbo iwa mimọ́ Rẹ̀; ti a yà sọtọ kuro ninu ẹlẹṣẹ, ṣugbọn eyi ki i ṣe pe o gba ara Rẹ̀ kuro lọwọ awọn ẹlẹṣẹ. Awọn Farisi mú ẹ̀sun wá pe O n bá awọn ẹlẹṣẹ jẹun a si n ri I lọdọ wọn. Itumọ eyi ni pe O ya ara Rẹ̀ si ọtọ kuro ninu ẹ̀ṣẹ ati aiṣedeedee wọn, nitori kò ni ọwọ́ ninu iwa buburu wọn. Bakan naa ni awọn eniyan Ọlọrun n ya ara wọn si ọtọ kuro lọdọ awọn ẹlẹṣẹ -- ṣugbọn ki i ṣe lati fi hàn pe “wọn jẹ́ ẹni ti o mọ́ jù.”

**“Ẹniti kò ni lati mã kọ́ rubọ lojojumọ, bi awọn olori alufa wọnni, fun ẹ̀ṣẹ ti ara rẹ̀. . . .”**

Oun kò ni ẹ̀ṣẹ. Bi o ba ka awọn Ofin Lefitiku, iwọ yoo ri i pe nigba ti awọn alufaa ba wá rú ẹbọ, wọn a maa fi akọ maluu rú ẹbọ; wọn a mu ẹjẹ akọ maluu yii lọ si ibi pẹpẹ lati kọ́ fi rú ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ ara wọn. Awọn wọnyii jẹ́ alufaa ti n jọsin ni ẹgbẹẹgbẹ. Lẹyin eyi wọn a fi ẹjẹ yii wọ́n pẹpẹ lati sọ ọ di mimọ́. Nigba naa ni wọn o rú ẹbọ igba keji, wọǹ a si fi ẹjẹ yii ṣe irubọ fun ẹ̀ṣẹ awọn eniyan gẹgẹ bi wọn ti n ṣe ni Ọjọ Etutu. Ọjọ yii ni Olori alufaa maa n lọ si Ibi Mimọ́ Julọ. Eyi n ṣẹlẹ ni ọjọ kẹwaa oṣu keje ṣaaju Ajọ Agọ, lẹyin ikore.

Ọjọ Etutu yii jẹ́ apẹẹrẹ ọjọ oore-ọfẹ ninu eyi ti Jesu Kristi di ewurẹ idasilẹlọ, ki i ṣe fun awọn Ju nikan, bi ko ṣe fun gbogbo agbaye.

**Ẹbọ Pipe**

**“. . . . . nidtori eyi li o ti ṣe lẹ̃kan-ṣoṣo, nigbati o fi ara rẹ̀ rubọ.’**

Ẹbọ ti Jesu fi ara Rẹ̀ rú wà fun gbogbo igba. Gẹgẹ bi a ti n fi eniyan si ipo oye alufaa lati iran-de-iran, bakan naa ni a n ṣe irubọ yii lati igba-de-igba. Olori alufaa a maa tún ẹbọ yii rú ni ẹẹkan lọdun, bẹẹ ni awọn alufaa ni ipa ti wọn a maa rú ẹbọ ni oroowurọ ati ni alaalẹ. Irubọ yii kò dẹkun niwọn igba ti Agọ ati Tẹmpili wà ni iduro. Oluwa ṣe ilana Ofin ni ọna ti awọn eniyan Rẹ̀ le maa wà ni isopọ ati idapọ pẹlu Rẹ̀ ni igbakuugba. Bi isin wa ba di ti ode-ara, ti ijọsin wa si di àṣa, a ti sọ koko rẹ̀ nù, igi lasan ni a n gbé lọwọ lai si ori aake. Ibi ti ijọ alafẹnujẹ ni ode oni ti kuna ni eyi.

Jesu fi ara Rẹ̀ rú ẹbọ ni ẹẹkan ṣoṣo, ẹbọ àrúkún ati àrúdà ti ko ni pe a n tun un rú titi lọ. Jesu fi ara Rẹ̀ rubọ ni ẹẹkan ṣoṣo, O si ti wà fun gbogbo agbaye lati igba ni titi aye ailopin, fun olukuluku ọkunrin, obinrin ati ọmọde.